# IROHIN IMỌLẸ

IM LE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No, 725 MONDAY, JUNE 22, 1964 (2d)

## Ọlọpa Kan Ji Sokoto Gbe !

KADUNA:— Oju gba gbogbo enia ti fun Ọdaran Ọlọpa kan, Ahmadu Sale, ẹni Ọdun mẹrindinlogbọn ti awọn Ọlọpa mu wa siwaju adajọ Ile ẹjọ kekere fun ẹsun ole jija ni Ọjọ Ẹti ti iṣe Ọjọ kokandinlogun Oṣu yi,

Ẹsun ti Ọlọpa ti o ba Ọdaran Ọlọpa ṣẹjọ fi sun niwaju adajọ ni pe Ọdaran Ọlọpa na wọnu iyara Ọlọpa kan Daniel Sashere lọ ninu Baraki awọn Ọlọpa nigbati ko si Onitọhun nile, o si gbe sokoto kan ninu yara rẹ iye owo rẹ jẹ ponun meji (£2) tabili kan ati ẹwu kekere kan.

Nigbati Ọlọpa na de lati ibi iṣẹ ti o si ṣe akiyesi pe ole kan ti ko on lẹru lọ ni o ba pe gbogbo awọn Ọlọpa jọ ni Baraki ti o si sọ fun wọn. Lẹhin na ni o to mọ pe Ọdaran na lọ ko on lẹru lọ.

Ninu ẹjọ ti Ọdaran na rọ lati fi gba ara rẹ sile, o ṣe alaye pe on ko ji sokoto na gbe o ni on fẹ sokoto wulini na fun Ọdaran nigbati o ṣẹṣẹ nlọ si Ile-iwe lati kọ iṣẹ Ọlọpa. Ṣugbọn lati igbana ni on ti mbere Owo lọwọ rẹ ti ko san, ni on ba lọ mu sokoto na pe, "bi o kọ ba ni sawo, fun mi ni sokoto pada"

Ṣugbọn adajọ na ni o ya on lẹnu lati ri ohunti Ọlọpa ṣe nigbati o mọ Ofin ti o si jẹ pe on ti yẹ ki o ma a fi apere rere lelẹ fun awọn ẹlomiran, ni adajọ ba ni ki o lọ fi ẹwọn Oṣu mẹfa jura.

# ẸGBA A — MẸTA (6,000) ÀWỌN NỌỌSI FẸ DA IṢẸ SILẸ !

EKO:- Gbogbo ile lo kunsọṣọ ti ẹsẹ ko si gbero fun ogunlọgọ awọn Nọọsi ti nwọn se ipade nla kan ni opin ọsẹ ti o kọja yi lori ẹkunwo owo oṣu eyiti Igbimọ oluwadi Morgan ti palaṣẹ fun Apapọ Ijọba Naijiria lati san fun awọn oṣiṣẹ.

Awọn Nọọsi na sọ ninu ipade wọn pe, Igbimọ Morgan ti sọ pe, "ki Apapọ Ijọba Naijiria yan Igbimọ kan pataki lọtọ lati se iwadi eyi ti yio sọ aiye ti o tọ ti o si yẹ lati fi kun owo oṣu awọn Nọọsi ati gbogbo awọn Tisa."

Awọn Nọọsi na sọ ninu ipade na pe lati igbati Abayọri iwadi Igbimọ Morgan ti jade ti o si ṣe alaye yin. Apapọ Ijọba ko sọ ohun, kan lori eto na, bẹni awọn ko si gbọ pe Ijọba nṣe eto kan pataki labẹlẹ lori ọran na.

Ninu ipinnu ti nwọn ṣe lẹhin ọpọlọpọ alaye, gbogbo awọn Igbimọ ẹgbẹ awọn Nọọsi na wa kesi Ọlọla olo ye Dokita Moses Adekoyejọ Majẹkodunmi, Minista Alamojuto eto ilera fun Apapọ Ijọba Naijiria lori ọrọ na.

Gẹgẹbi alaye ti ọgbẹni Nathaniel Cole Olu-Akọwe ẹgbẹ awọn Nọọsi na ṣe fun Oniwe wa Ejon'gboro ni ipari ọsẹ to kọja yi, o ni, o dabi ẹnipe, Ijọba ko fẹ ṣe ipinnu gbodogi kan lori eto na, eyi si jẹ ohunti o nṣe awọn ni kayefi.

Olu-akọwe awọn ẹgbẹ Nọọsi na tun wa kọwe pa teki kan si ọgbẹni J. C. Obande, Minista Alamojuto eto idasilẹ iṣẹ Aje pe, ki awọn tete wa ọna lati ṣe ipinnu ohunti nwọn ba ro pe, o tọ o si yẹ ki nwọn ṣe, ki awọn Tiṣa ati Nọọsi yio fi ni ẹkunwo, owo-oṣu.

Iwe na ṣe alaye pe, iṣẹ Minista na ni lati ma a ṣe ohunti yio jẹ ifẹ ọkan awọn oṣiṣẹ ati ti gbogbo enia, ki idagbasoke ohun alafia iṣẹ Aje o le ma a lọ siwaju ni gbogbo igba ni orilẹ ede yi laiko si ohun idiwọ kan niwaju Ijọba, eyiti igbẹhin rẹ le mu abamọ dani loni tabi lẹhin ọla.

Siwaju si I, iwe na tun sọ pe, niwọn igbati Apapọ Ijọba ti gba pe, iṣẹ awọn ni lati ṣe ohun gbogbo lori eto iwadi ẹkunwo ow o oṣu eyiti Igbimọ Oluwadi Morgan ṣe, fun awọn Ijọba Ipinlẹ, awọn lero pe, Minista na ko ni fi eto ti o yẹ lati ṣe laiko ṣe.

Ninu iwe kan ti awọn ẹgbẹ Nọọsi na tun fi ranṣẹ si onirohin wa nile ni owurọ ana, nwọn ṣe alaye sibẹ pe, "gbogbo awọn Nọọsi yika orilẹ ede yi, ti ṣe ipade, awọn si ti gba aṣẹ lati ọdọ Igbimọ Alaṣẹ ẹkele ẹgbẹ na pe, ki gbogbo awọn wa ni imurasilẹ, ki awọn si ma a ṣe ireti fun ohunkohun ti o le ṣẹlẹ laipẹ yi.

Ni ipari iwe ti awọn ọmọ ẹgbẹ na ran akọwe wọn lati lọ ri Minista na, awọn ọmọ ẹgbẹ na sọ pe, A fun Ijọba ni ọjọ mọkanlelọgbọn pere lati fun wa ni esi iwe wa yi, bi a ko ba si ri esi iwe na gba, lẹhin ọjọ mọkanlelogun na, gbogboawa Nọọsi ni gbogbo ile iwosan yika Orilẹ ede yi ni yio binu da iṣẹ silẹ.

Onirohin wa kan fi ye wa pe, nigbati awọn oṣiṣẹ da iṣẹ silẹ ni ijejilelogun eyiti o pari ni ijẹjọ awọn Nọọsi ko da iṣẹ silẹ ni gbogbo igbana.

O tun ṣe alaye ninu ọrọ rẹ pe, ọpọlọpọ awọn alaisan ni nwọn fẹ amejuto ni gbogbo Ile Iwosan, awọn aboyun ti awọn fẹ bi ọmọ ati awọn ti nwọn ko le dide jeun ati awọn ti ko le dide lọ tabi yagbẹ.

Onirohin wa kan ran wa leti pe ogorun ọkẹ ponun (£2.000.000) ti Ijọba padanu larin asiko ti awọn oṣiṣẹ da iṣẹ silẹ na, eyiti Ijọba ko le ri padamọ.

## HA ERIN NLA WO !! AJANAKU LỌ L'ESE OMI !!!

EKO:- Ni deede agogo meji ọsan ana ọjọ Aiku ni gbogbo inu ile ati ode Ijọ Ọlọrun "Ebenezer Baptist Church, kun ti ẹsẹ ko si gbero fun awọn enia jankanjankan ti nwọn wa si Ṣọọsi lati se isin ijade oku fun ologbe Ẹniọwọ Alufa Robert Adegbitẹ Daniel Tẹlla, ẹniti ofilẹsasọbora ni ọjọ Aje ti ise ọjọ kẹjọ osu yi ninu ile rẹ ni nọmba 50, Campbell Street, lẹhin ti o ti di ẹni ọdun mẹrindinladọrun (86 years) laiye.



OLOGBE ẸNI-ỌWỌ R. A. D. TẸLLA
Alufa Ijọ Ebenezer Baptist Church

Lẹsẹkẹsẹ ti o jade laiye ni Okiki ti kan kakiri gbogbo Na jiria ati oke okun ti awọn Alufa Ijọ Ọlọrun si sare wa si Eko ti nwọn si ṣe isinku Baba Oninu ire na ni Ọjọ Abamẹta ti iṣe Ọjọ kẹtala oṣu yi.

Ṣugbọn nigbati o tun di Ọsan ana ni awọn Ọmọlo-

WO OJU EWE KẸFA

# ALAWADA ỌYỌ !

**Alawada:** Ẹ ku owurọ o Olotu ṣe ẹ ko ri ọgi-nnitin yi o ?

**Olotu:** Ọla nyin gan an na ni ko fi jẹki nri olotu na ki kukuru alafia ni mo ji o kini kan ko si lara mi nitoripe "piri ni ologo nji a kii Ba Olokunrun ẹiyẹ ni ori itẹ

**Alawada:** Owe ti ẹ pa ko ye mi Olotu, ẹ ni ọla t'emi ni ko jẹki ẹ fi ri otutu, ko ye mi rara

**Olotu:** Alawada Ọyọ, awada rẹ tilẹ pọju, ọrọ ti mo sọ ti ye ọ yekeyeke ewo ni aburo maa fun mi ni gogongo ki mba le fọ ifokufọ

**Alawada:** Ẹniti oba bere ọrọ ni o nfẹ idi rẹ gbọ ọrọ ti ko ye mi ni mo mbere yẹn o.

**Olotu:** Jẹki a pa ọrọ na ti ka ki a si ma a ba ere aniyan bọ, ngo sọ itumọ rẹ fun ọ ni Ọjọ waju.

**Alawada:** Mo wa gbadun akọlẹ ọrọ iwe nyin, Olotu

**Olotu:** Kini akọlẹ ọrọ wa na o?

**Alawada:** Akọlẹ ọrọ yin na ka bayi pe "Imọlẹ Ọrẹ Aiye. Tẹni gbogbo lawa. Iyẹn ni pe asọtunso si maba ibikanjẹ ni yin?

**Olotu:** Bi o ti ri gan an ni o wi yẹn.

**Alawada:** Olotu, iyẹn ni pe ẹ faramọ ẹgbẹ "Dọmọnu" ti nwọn fẹ ko ọmọ Yoruba ta fun awọn ẹni Ọlọrun o rẹru fori ti igi

**Olotu:** Bibẹkọ o, Alawada ko faramọ ẹgbẹ "Dọmọ nu" bikoṣe ẹgbẹ "Kọmọjọ"




**Alawada:** Tani ẹgbẹ "Dọmọ nu", tani ẹgbẹ "Kọmọjọ?

**Olotu:** Ẹgbẹ jagunlabi ọkọlala kọ igba ori 'Dọmọnu" Baba ni Ikẹnnẹ ni o ni ẹgbẹ "kọmọjọ"

**Alawada:** Olotu, orukọ ni i maa ro enia, ẹda t o ba kọ ẹgbẹ „Dọmọnu" jọ, ko ni ọmọ lẹhin, ẹniti o da ẹgbẹ kọmọjọ ko ni lọmọ lẹhin Jantirẹrẹ.

**Olotu:** Ki lo tun nsọ yi Alawada ṣebi odi ẹgbẹ mẹrin ti jagunlabi da silẹ lario ọdun kan ti gbogbo rẹ tuka yangan, ki o to tun wa da ẹgbẹ 'Dọmọnu silẹ

**Alawada:** Ma woye Olotu eyiti o da silẹ ti fẹrẹ fọ tan, ni ti Eko o fọ tan yanganyangan. N jẹ ẹ gbọ pe Mallam Banni ti iṣe Alaga Ẹgbẹ Imọlẹ Owurọ l' Eko ti kọ ẹgbẹ na silẹ atipe o ti sọ ẹgbẹ na di ẹgbẹ Ọdọ Afẹnifẹre.

**Olotu:** Ninu ọrọ Alapara Ibadan ni mo ti ka pe, o ti sọ ẹgbẹ na di ẹgbẹ Ọdọ Afẹnifẹre.

**Alawada:** Emi papa kaa, mo si ti lọ ba Alapara lati fọrọ jomitoro ọrọ lẹnu rẹ nipati ọrọ Mallam na ohun ti nsi jijọ sọ ni yi.

## ALAWADA PADE ALAPARA

**Alawada:** Ẹ ku iyalẹta o Alagba, ẹ dakun mo bere Alapara Ibadan o

**Alapara:** Ṣe ko si nkan o?

**Alawada:** Alafia ni o.

**Alapara:** Kini ẹ nwa f ua?

**Alawada:** Fun rere ni o, ṣe ko si ni ile ni?

**Alapara:** Ko si ni ile.

**Alawada:** Ti o bade, ki ẹ jiṣẹ fun pe. Alawada Ọyọ de ile mo ni ki nfi kan de ọdọ rẹ paa ni o.

Bayi ni Alapara sọ mọ mi o si fi ifẹnukonu kimi pe, mo ku atijọ. o mu mi wọ iyewu lọ, o ṣi ja mi ni aha ọti meji, nigbati mo fi ẹsẹ mejeji tilẹ tan ni mo wa bẹrẹsi tu kẹkẹ ọrọ silẹ.

## ALAWADA ATI ALAPARA TẸNU BỌ ỌRỌ SISỌ

**Alapara:** Ẹ ku abọ o. Olotu ṣe alafia ni ẹ de, ile nkọ?

**Alawada:** Alafia ni; ṣe Jada ni mo ba nyin? Inu mi dun lati mọ nyin loni o.

**Alapara:** Bẹẹni emi papa, "Emi oke f'oju kan ti odo" niyẹn o.

**Alawada:** Ajumọṣepọ wa ko ni bajẹ lagbara Odudua.

**Alapara:** Amin, Aṣẹ o.

**Alawada:** Kini kan ni mo wa wadi lọdọ yin nje otitọ ni Mallam Banni fi ẹgbẹ "Imọlẹ Owurọ ti iwe Irohin imole Owuro da sile bi ?

**Alapara:** Olotu ni nitoripe moti wadi lenu mallam Bani o si sọ fun mi pe bẹẹ ni ọrọ na ri gan au

**Alawada;** Inu mi yio dun bi ẹ ba le ṣapejuwe ile mallam na fun mi ki enu papa ba le ri okodoro ọrọ na

**Alapara;** Nọnba "Onipara Street l'Eko ni o ngbe

**Alawada:** Ẹdakun mo tọrọ gafara lọdọ oju, mo fẹ maa lọ ma

**Alapara:** Nigbawo ni a to tun rira o Alawada ?

**Alawada:** Ti Oluwa ko ba fuad nu ngo digbẹrẹ Ọdọ yin ni ọsẹ ti o mbọ

**Alapara;** Odigba o, ka fi ire pade ọ Alawada fi ife oti kan tẹẹ mọlẹ, ni O ba wa irin kun ẹsẹ re

## ALAWADA KAN MALLAM BANNI LARA

**Alawada:** Gafara onile o !

**Mallam:** Ọlọrun lo ni o le maa wolẹ ẹ maa rọra Tani ẹ bere o ?

**Alapara:** Mallam Banni ni mo bere o

**Mallam:** Emi ti mo njẹ bẹ ni yi se ko si nkan o ?

**Alawada:** Orukọ emi na ni Alawada Ọyọ,

**Mallam:** Orukọ rẹ ma tilẹ farajọ ti ọrẹ mi Alapara Ibadan ?

**Alapara:** Bẹẹ nani ọrẹ ni awa mejeji iṣe

**Mallam:** A fi bẹẹ na nisisiyi ni inu mi wa yọ si ọ lati gba ọ lọwọ tẹsẹ, kini o ba wa o ?

**Alawada;** Mo gbọ pe ẹ ti fi ẹgbẹ Imọlẹ Owurọ silẹ,

**Mallam:** Lati ọjọ wo niyẹn kọ, emi ati awọn ẹgbẹ mi ti fi ẹgbẹ na silẹ da ẹgbẹ ọdọ fẹnifẹre sile,

**Alawada** Nibo ni ẹ da silẹ si ?

**Mallam:** Ebute Mẹtta ni a d silẹ si.

**Alawada:** Nigbawo ni ẹ o tun ṣe ipade yin ?

**Mallam** Ngo maa jẹki o gbọ lọla ki o le jade ninu iwe Irohin Imọlẹ nyin

**Alawada** Ẹ ṣeun pupọ Mallam fun ifarabalẹ ti ẹ fi dami lohun awọn ibere mi, Oluwa ko ṣe ati lehin fun yin Amin.

**Mallam:** Emi ki i ṣe Hausa tabi Yoruba Fulani ni emi iṣ ẹ, ṣugbọn mọ daju pe, ẹgbẹ Ọlọpẹ nikanṣoṣo ni o pe ni Nijiria.

**Alawada:** Bi o ṣe ti ati ile mi ni Ọlọpẹ ni awa yio ma ṣe titi di ọjọ iku wa

**Mallam:** Aila nsunmọ, mo fẹ lọ si Mọṣalaṣi, dakun Alawada yọnda ni o.

**Alawada:** Ka fire pade o, ngo tun pada ọjọ ti ẹ ba ṣe ipade ati ibiti ẹ o ti ṣe o, Ka pade layọ o Alawada maṣai ba mi ki Alapara t i o ba ri o.

## ALAWADA PADA DE ỌDỌ OLOTU

**Alawada:** Ẹ ku ile o Olotu

**Olotu:** Ṣe dada lo ṣe o ?

**Alawada;** Alafia ni o

**Olotu:** Ṣe dada ni o ba Alapara ati Mallm Banki?

**Alawada:** Alafia ni mo ba awon mejeji o.

**Olotu;** Kini Mallam Banni wi fun ẹ ?

**Alawada;** Wọnle ni o taku mọ ẹgbẹ Imọle Owurọ lọwọ oni, ohun ti o jẹki on fi ẹgbẹ Imọle Owurọ ti iṣe alakẹh'n "Dọmọnu ni pe nwọn ki i gbe ọmọ ni agbeye afi agbeku.

**Olotu:** Ni kukuru ẹgbẹ Imọlẹ Owurọ fidi janni Eko.

**Alawada:** O ti fori sanpọn bẹẹni yio si se ni gbogbo ilu yoku lagbara Ọlọrun

**Olotu:** Ka fi ire pade ni ọsẹ ti o mbọ o Alawada

Alawada si dagbere fun Olotu pe odigboṣe o.

**E Ma ka Iwe Irohin Imọlẹ lojoojumọ**

# Ijoba Ibilę Ogbomoshọ Yio Na Ọkę Męjọ Pọnun

OGBOMOSHO:- Ijoba ibilę Ogbomọsho ni ękun Ọshun yio na £163, 000 fun ọdun 1964 si 1965. Eleyi de ọwọ wa lati ęnu akọwe agba ti igbimọ na, ọgbęni E A Oke.

Ninu owo na £50, 00 yio lọ fun eto işę eyi si pęlu ti kikọ ile awọn ọlọpa ibilę titun ati fun kikọ ile igbimọ na eyi ti yio jẹ £35, 000 nigbati nwọn ba kọ tan igbimọ na yio na £41,-000 lori ękọ lati fun awọn ogun awọn ọmọ ile ękọ ni ękọ ọfę lọ si ękọ giga ati lati kọ ękọ işę awọn Olukọ.

Awọn alaşę Ijoba Ibilę Ogbomọshọ ti nşe eto na lọwọ bayi bi ilọsiwaju ati idagbasoke on Ijoba rere yio şe wa ninu ilu na ati agbegbe rę.

## YĘ IRAWỌ RĘ WO

AQUARIUS (Jan 21-Feb 19) Ọrę rę kan ęni ti iwọ o kasi ni ęniti yio gbe ọ lęsę nipa ọrọ kan ti o sọ, ko yę ki o ma ba işę lọ pęlu rę lailoya.

PISCE (Feb 20-Mar 20) Ohun ti mo ntęnumọ fun ọ ni pe ipinnu kan ti o fę şe nipa ọrọ ile rę tun lọ sọrọ na loju ọrę rę kan ti o fęran yio si gba ọ ni imọran

ARIES (Mar 21-April 20) Lọ bęrę lati ipilęşę wa, awọn yoku yio ma bọwọ fun ọ nişişę bayi ina ariki rę ya majo

TAURUS (April 21-May 22) Bi aba sọ wipe ki a ma yan ęniti o nşe dara iwọ gan lo yę ki a yan jęki gbogbo enia gba pe iwọ li ęni ti o yę lati yan, nitori iwọ ko nşe ajoro.

GEMINI (May 23-June 21) Ko nşe oni tabi ana ni ija onija ma ndi tirę, ohun ayọ kan yio fi bę silę larin ile rę ti yio mu inu rę dun gidigidi.

CANCER (June 22-July 22) Şọra rę ki nwọn ma-şe purọ mọọ ohun ti o yę ki o şe ni wipe ki o wadi ęniti o purọ na ki osi mọọ, ki oju leti eke.

LEO (July 23-Aug 22) Enia rę kan ti o wa nidalę tabi ti o gba isimi lọ siti kan, yio ti ma reti rę. Şe alikun işę rę lọsan yi, yio ję rere nigbęhin fun ọ.

VIRGO (Aug 23-Sept 22) Gbogbo ọjọ oni yio ję rere fun ọ jalę ęnikan ti o ma nşe ju yio wa fi ara mọ ọ.

LIBRA (Sept 23 - Oct 22) Sọ irin ęsę rę loni nitotọ awọn alaniku enia ti o ma fi ibiru la işę enia ję laiję wipe iwọ lilę ni ęsę rę.

SCOPIO (Oct 23 - Nov 22) Jęki awọn ara ode si tirę sọ nibi ere igbadun ti nwọn fę şe lapęyi, iwọ yio gbayi nibę rępętę.

SAGITTARIUS (Nov - Dec) Maşe ję ęniti yio ma gba ọrọ agbọsọ gbọ, ogunlọgọ iru awọn ọrọ bę ko fo tęlę,

CAPRICORN (Dec 23 - Jan 20) Ohun kan ti iwo ko ro tęlę ni yio şeranlọwọ fun ọ towo tọmọ, iwọ o si gbe işę na le ęni rę kan lọwọ to ję ara ębi rę.

## E ma a Ka we Irohin Imọlę Lojojumọ Ki ę si maa Polowo Ọja Nyin Sinu Rę Pęlu


## BI O BA NI

# Iwe—Titę

FUN

**Lilo nibi Işę rę tabi orişirişi iwe itufọ tabi ijade Oku**

ATI

**Iwe Igbeyawo**

TETE KỌWE SI ILE-IŞĘ-ẸRỌ ITĘWE

**Modupę Printing Press**
16, Bamgboşe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.

KETE KETE NI ẸRỌ ITĘWE WA NHAN
OWO POKU NI A SI NGBA
IROHIN KO TO AFOJUBA
Dan wa ni lęękanşoşo ko si ri iyatọ



## EGBOGI JĘDIJĘDI

BERE EGBOGI



### "CYCLOVEN"

Aworan oke yi fi han gbangba ibiti Jędijędi rę gba wa lara re si nyọ o lęnu nigbagbogbo.Ibę ni a npe ni "omusu tabi iho idi enia ibiti a ma ngbe şe igbọnsę. Arun Jędijędi je okan ninu amodi ti o buru ni pataki fun Ọkunrin ti o si lagbara pupọ lati şe iwosan rę patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri ode nisiyi ti nwọn ma a po-lowo wọn fun iwosan rę şugbọn boya la leri męwa ninu awọn ogun ti ole şe iwosan arun yi daradara. Awọn ęlomiran lero wipe boyabi wọn ba lọ si ile lati lọ ke eyiti oba nyọ j de lati omuşu ku nipa bę awọn o bọ lọwọ rę patapata.

Şugbọn awa o ro bę rara Lęhin ọdun diẹ iyọnu rę ylo si tun bęrę bakana Orişirişi Jędijędi ni o wa, Ekini ti o bęrę nipa aiko ma şe igbọsę dede tabi lojojumọ ęlomiran nipa ijoko ni ojukanna pęlu lojojumọ tabi gigun kękę ologere (Basikulu) pupọ ęlomiran ęwę nipa j'ję Şuga tabi oniruru ohun adidun pupọ pupęju nigbakugba Jędi-jędi orişirişi ni o wa, ewo ni tirę? Bi o nyọ jade ninu omuşu tabi ti o ba nmu ęję wa lęhin igbọnsę tabi ti o ba nyọ ti o ba şe igbọnsę tan ni tabi ti orin ọ ninu omuşu ni eyikeyi ti o ba ję bere egbogi "CYCLOVEN" ti awọn Oyinbo Jamani şęşę wa idi rę kio si danwo orişi męta ni daju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jędijędi patapata alafia yio de si ọ ekeji rę ko si ninu gbogbo egbegi atata nigboro Naijiria jakejado bere ni ni:

NIGERIA MEDICINE STORES
4, Tinubu Square, Lagos

Waterloo Medicine Stores
8 Palmchurch Street, Lagos
Phone: 22878 Nigeria, (Ọja Ita Faji

ATI AWỌN ŞỌBU
IŞĘ OLODUMARE DISPENSARY OKE BỌLA IBADAN

# IROHIN IMOLE

IMOLẸ ORẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 725 MONDAY JUNE 22, 1964 (2D)


## Ijamba Şe Ole, Onile Kan Mọ!

IK ẸJA:- Ọgbẹni Funmilayọ Wickbiffe adajọ Agba Ile ẹjọ kekere Ikẹja, şe idajọ pe ki ọdaran kan, Yinka Adeyẹmi, eni ọgbọn ọdun ki o lọ si ẹwọn ọdun meji nitoripe o jẹbi ẹsun ole ti awọn ọlọpa mu fun, ni ọjọ Ọjọ'Bọ ti işe ọjọ kejidinlogun oşu kẹfa ọdun yi.

Ọlọpa ti o ba ọdaran ni şejọ şe ala ye fun Ile ẹjọ pe, ninu ọsẹ to kọ ja, ti gbogbo enia fẹ ma wọ mọto larin ọja Mushin ni ọdaran na ba ti ọwọ bọ inu apo ẹwu Ọgbẹni Ọmọbọwale Leigh o si ji ponun mẹdogun (£15) gbe.

Şugbọn bi o fẹ yọ ọwọ jade ni awọn enia ti o wa nitosi ti nwọn ri ọdaran na ba ragabu rẹ larin ọja. Lẹsẹkẹsẹ ni gbogbo ero ọja parojọ le ọdaran na lo ri, nwọn si mu lọ si Tesan Ọlọpa.

Gbogbo kotu lo rẹrin arintakiti nigbati ọlọpa rojọ tan ti ọdaran na si sọ fun adajọ, nigbati adajọ bere lọwọ rẹ pe "kini o fẹ wi? Ti ọdaran na si sọ fun adajọ pe, 'kini o fẹ ki nwi, nitootọ ni mo gbe owo na, ebi lo si npa mi ti mo fi jale ki işe pe mo fẹ j le t lẹ, şu gbọn nigbati ebi de nkọ ?

Ọdaran na wa sọ fun adajọ pe, "Tete şe idajọ to fẹ şe, maşe lo asiko ararẹ şofo, ẹlẹri wo lo tun nwa? O ti d! meji ti mo ti nwa işẹ ti nko si ri. Ni adajọ ba fi şe idajọ gẹgẹbi a ti wi si oke iwe yi.

# AARA PA ỌMỌ ILE-IWE KAN!

JOS:-- Idaamu nla ba gbogbo awọn ati Olukọ awọn enia ti nwọn wa ni osi nigbati awọn ọmọ Ile iwe kan, "Lady of Fatima School" jade lati şere ti Aara nla kan san ti o si pa ọmọ Ile-iwe kan, Ignatius Udi, to si ku bamubamu.

Irohin awọn alaşẹ Ile-iwe na fi ye wa pe, awọn ọmọ Ile iwe na ti jade işere ninu Ile iwe wọn, gbogbo awọn ọmọ na si bọsi Ori Ọdan Ọgba ile iwe wọn.

Bi awọn ọmọ na ti nsere ni ojo nla kan su, şugbọn ojo na ko ti rọ, Bi awọn alaşẹ ile iwe na ti fẹ lu agogo fun awọn ọmọ na lati wọle ni aara nla kan san; ti ẹdun aara na si bọ si arin awọn ọmọ na nibiti nwọn gbe nşare;

Lẹsẹkẹsẹ lo pa ọmọ ile-iwe kan ti orukọ rẹ njẹ Ignatius Udi, ẹni ọdun mejila ti o wa ni iwe kẹrin ninu ile iwe na,

Irohin fi ye wa pe loju—kanna ni ọmọ na ku ti aara na si tun se awọn ọmọ meji miran ti nwọn jijọ nsere lese

Lẹsẹkẹsẹ ni gbogbo awọn olukọ Ile-iwe na ati awọn olonjẹ ba sure jade ti wọn si wa gbe oku ọmọ na ati awọn meji miran ti nwọn fi ara pa ninu ijamba nla na.

Lojukanna ni gbogbo Ile iwe na daru ti awọn olukọ si gbe awọn ọmọ meji na lọ si Ile-iwosan fun itọju nigbati nwọn gbe oku ọ m ọ na lọ si Ile-iwoşan lakulaku fun ayẹwo awọn Dọkita.

Irohin fi ye wa pe gbogbo awọn Olukọ Ile iwe na ni nwọn ko le şişẹ mọ ni ọjọ na nitori ohun ti o şẹlẹ yi. Nwọn si paşẹ f u n gbogbo awọn ọmọ Ile iwe pe ki nwọn ma a lọ si Ile, ki nwọn jẹki o di owurọ yi ki gbogbo wọn to tun wa si Ile iwe.

Ki Ọlorun fun awọn ọmọ ti nwọn wa ni Ile Iwosan ni alafia ki o si t u obi ọmọ t o k u ninu o.


## AFRICAN SPECIAL

- Full tropicalisation and underbody protection plates
- Strong and comfortable suspension.
- Outstanding road holding.
- Modern workshops and spare parts stores, manned by Factory Trained Staff.
- HIGH RESALE VALUE.

DON'T FORGET THAT YOU CAN ALSO TRADE IN YOUR OLD MERCEDES-BENZ OR RENAULT CAR!

MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, APAPA, & EBUTE METTA, IBADAN KADUNA, KANO JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT HARCOURT & ABA.


## HA! ERIN NLA WO!!

ku Baba na tun şe isin iranti iku Baba wọn ninu Ile Ọlọrun ti Baba na ti nşişẹ nigba aiye rẹ.

Alufa Ijọ First Baptist Church Eko, Eniọwọ Dọkita E A. Dahunsi ti o şe iwasu isin na lara şe iyin Baba na gẹgẹbi Alagbara, Oloto ati Olufẹkansin, ti o ba Ọlọrun rin, ti o si ku iku Olododo.

Nigbati isin na pari, ni gbogbo awọn enia na wa lọ sinu ile Sinima CAPITOL ti gbogbo wọn si fi ata pa ẹnu titi ilẹ ọjọ na fi şu.

Ki Ọlọrun da gbogbo awọn ọmọ baba oninure na si, ki o si tu iyawo rẹ ninu, ki o si pese Oluşọ Agutan rere, ti o le şişẹ tọkantọkan bi iru baba na fun Ijọ Ebenezer ti o fi silẹ.


Printed and Published by Modupe Printing Press 16, Bamgbose Street Lagos Phone 21985
Editor:- TUNJI ADEOSUN 45. Campbell Street Lagos 22/6/64